# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KÍNÍ, ỌDÚN 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## PÀṢẸ FÚN ỌDÚN

**JÁNÚÁRÌ 2022 PÀṢẸ FÚN ỌDÚN**

**ỌRỌ AGBÁRA**

1. Gbogbo igbimọ ati imọran buburu, ti wọn gbero lodi si ojurere mi ninu ọdun yii yoo kuna gẹgẹ bi o ti ri fun Ahitofẹli, ní orúkọ Jésù.
2. Ìfòróróyàn fún ojúrere atòkèwá, ayé mi wà fún ọ nínú ọdún yìí, wọlé wá, ní orúkọ Jésù.
3. Ibi gbogbo tímo bá lọ nínú ọdún yìí, ààbò atòkèwá yóò jẹ́ tèmi, ní orúkọ Jésù.
4. Ní ọdún yìí, ẹnubodè àánú àti ojúrere yóò ṣí sílẹ̀ fún mi, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa àánú Rẹ, Olúwa, jẹ́ kí ojúrere tíkòwọ́pọ̀ yalu ayé mi nínú ọdún yìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìdíwọ́ àti ìdenà sí ìṣerere mi yóò gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
7. Ojúrere àti àánú atòkèwá kì yóò kúrò nínú ayé mi jálẹ̀ ọdún yìí, ní orúkọ Jésù.

**ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn kó gbógun tìmí nípa ṣẹ̀ àlá nínú ọdún yìí, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo kòtò tí àwọn ìránṣẹ́ ikú gbẹ́ fún ayé mi nínú ọdún yìí yóò gbe àwọn tó gbẹ mì, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìpinnu, ìdájọ́ àti gbólóhùn àjọ àjẹ́ lórí ayé mi nínú ọdún yìí yóò rún jégéjégé, ní orúkọ Jésù.
6. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, yọ́ dànù gbogbo gbólóhùn tí wọ́n yàn láti fàmílulẹ̀ nínú ọdún yìí, ní orúkọ Jésù.
7. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wa? Dìde, ṣèdájọ́ gbogbo ahọ́n tí wọ́n yàn kó dámilẹ́bi nínú ọdún yìí, ní orúkọ Jésù.